7

Ìṣàmúlò ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wu nínú àṣàyàn òwe àtiewì àpilẹ̀kọ Yorùbá fún ìdàgbàsókè àwùjọ

Salami, Èjítóyọ̀sí Ọláyẹmí

Àṣamọ̀

Àkíyèsí wa ni pé ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní àsìkò yìí, àyípadà ti dé bá bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ṣe rí tẹ́lẹ̀ yálà nípa ètò ọ̀rọ̀ ajé, ìṣèlú, ẹ̀kọ́, ìbágbépọ̀ ẹ̀dá láwùjọ àti àwọn ẹ̀ka ètò gbogbo tó wà fún ìdàgbàsókè àwùjọ. A wòye pé nínú àwọn iṣẹ́ tó wà nílẹ̀, kò fi bẹ́ẹ̀ sí iṣẹ́ tí ó wo ìṣàmúlò ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wù nínú àṣàyàn òwe àti ẹwì àpilẹ̀kọ Yorùbá fún ìdàgbàsókè àwùjọ. Èyí sì ni àlàfo tí iṣẹ́ yìí fẹ́ dí.Àwọn ìwé ewì àpilẹ̀kọ tí a ṣe àmúlò wọn ní Ìgbà Lonígbàáká, Àwọn Akéwì Ń Ṣàṣàrò, Ọmọlúàbí, Ọ̀tọ̀lórìn (Àkójọpọ̀ Ewì Òde-òní), Àkójọpọ Ewì Àpilẹ̀kọ fún Ètò Ẹ̀kọ́ Tuntun. A ka àwọn ewì náà láti ṣe àlàyé ìlò àwọn ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wù inú wọn. Òwe mẹ́rìnlélógúnni a lò. Àwọn ìwé òwetí a ṣe àfàyọ ewì nínú wọn ni Sheba (2006), Babádé (2008) pẹ̀lú Ọláwuyì àti Ọládiméjì (2011). Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbáraẹnigbépọ̀-àwùjọ-wo-lítíréṣọ̀ ni a lò fún iṣẹ́ yìí. Ìdí ni pé ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ kò dúró bákan náà títí, ó máa ń yí ni. Iṣẹ́ yìí tọ́ka sí ìlò ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wù nípa ṣíṣe àlàyé àpẹẹrẹ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ̀ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà bó se wà tẹ́lẹ̀ àti àyípadà tó dé bá wọn. Ó ṣe àlàyéipa rere àti búburú tí ìṣẹ̀lẹ̀ àlàbọrùndẹ̀wù ní lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ọ̀nà àbáyọ. Ó gba àwùjọ níyànjúpé bí ìṣẹ̀lẹ̀àwùjọ tilẹ̀ ń yí, síbẹ̀ àwọn àyè àti ipò kan wà tí kò bójú mu fún ẹ̀dá láti yí sí.

Kókó ọ̀rọ̀: Àyípadà, àlàbọrùn, ìdàgbàsókè, àwùjọ, ọ̀nà àbáyọ

Abstract

Our observation in the contemporary Nigeria is that there are changes in almost every aspect of its development, whether economic, political, social or education. It was noticed that there was little or no work on the use of new normal sayings in selected Yoruba proverbs and written poetries. This work intends to fill the gap. The written poetries used by the work are Ìgbàlọnígbàáká, Àwọn Akéwì Ń Ṣàṣàrò, Ọmọlúàbí, Ọ̀tọ̀lórìn, (Àkójọpọ̀ Ewì Òde-òní),Àkójọpọ̀ Ewì Àpilẹkọ fún Ètò Ẹ̀kọ́ Tuntun. The poetries are read and analyzed in accordance with their uses of new normal sayings. Twenty-four proverbs were used from proverb textbooks such as Sheba (2006), Babade (2008), Olawuyi and Oladimej (2011). The texts are

analyzed through the use of the Sociological theory of literature. The theory was chosen because situations in society are not static. The work identifies the new normal sayings by giving examples of situation in Nigeria as they were, and the changes they underwent. It explains the positive and negative impacts of new normal on the Nigerian situation. It recommends that even if situations change, it is not all changes that are desirable.

Keywords: Change, "àlàbọrùn", development, society, solution

Ìfáárà

Ìṣẹ̀lẹ̀ ilé ayé kò dúró lójú kan, yíyí ní í yí. Bí ó ti le yí síwájú náà ni ó le yí sẹ́yìn. Ìdàgbàsókè a máa bá àwùjọ nígbà tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú rẹ̀ bá ń yí síwájú tí ohun gbogbo sì ń lọ déédé tí ó sì rí bí ó ṣe yẹ kí ó rí.Bákan náà ni akùdé le bá ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ nígbà tí àwọn ohun kan kò bá lọ déédé tí wọn kò rí bí ó ṣe yẹ kí wọ́n rí, ìdàgbàsókè àwùjọ a sì máa fà sẹ́yìn. Èyí ni ó fà á tí ó fi jẹ́ pé ìpèdè tàbí àdúrà ọmọnìyàn nipé kí Elédùà mú ìgbà tó rọrùn wá nítorí àsìkó yìí kì í ṣe àsíkò tó rọrùn. Èyí a máa mú kí ẹ̀dá gba ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ohun mìíràn láàyè láti dípò èyí tí wọn fẹ́ ṣugbọ́n tí kò sí. Ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìgbà, èyí tí wọ́n gbà wọlé yìí a sí wá di bárakú fún wọn gẹ́gẹ́ bí àlàbọrùn tó dẹ̀wù.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àyípadà ni ó dé bá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní àsìkò yìí tí wọn kò rí bí wọn ṣe máa ń rí tẹ́lẹ̀, ìgbà tó dé ni ẹ̀dá inú rẹ̀ ń lò, bó ṣe gbà ni wọn ń ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan. Èyí kò sà dédé rí bẹ́ẹ̀ bíkòṣe àlùbá tí ó dé bá ètò ọ̀rọ̀ ajé, ètò ìṣèlú àti àwọn ẹ̀ka ètò yókù tí ó wà fún ìdàgbàsókè àwùjọ.

Ohun tí ó ṣe pàtàkì ni látimọ̀ àwọ́n ìṣẹ̀lẹ̀ tí àyípadà wọn di bárakú láwùjọ kí a sì ṣàlàyé wọn nípa báwo ló ṣe rí tẹ́lẹ̀? Báwo ló ṣe rí lásìkò àlàbọrùndẹ̀wù?, àti ìwà àti iṣe tí ó tọ̀nà láti gbà wọlé lásìkò náà.Bí èyí bá ṣe é ṣe, tolórí tẹlẹ́mù àwùjọ yóò le wá ọ̀nà àbáyọ sí ìṣẹ̀lẹ̀ tó dagun nípa mímọ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó yẹ, tí ó rọrùn tí ó sì dára láti tọ́jú.

Tíọ̀rì Àmúlò

Níwọ̀n ìgbà tí lítíréṣọ̀ jẹ mọ̀ ìgbékalẹ̀, ìrírí àti ìhùwàsí ọmọnìyàn láwùjọ èyí tí àwọn òǹkọ̀wé tí a lo iṣẹ́ wọn ṣe àkíyèsí, iṣẹ́ yìí yan Tíọ̀rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-àwùjọ-wo-lítíréṣ̀ọ láàyò. Hyppolyte Taine tí í ṣe onímọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó jẹ́ ọmọ orílẹ̀ èdè Faransé ni ó ṣẹ̀dá tíọ́rí yìí. Ó ṣẹdá tíọ̀rì yìí láàárín ọdún 1828-1893 gẹ́gẹ́ bí Adéyẹmí (2006:29) ṣe sọ.

Ìmọ̀ méjì ni ó parapọ̀ di tíọ̀rì yìí. Èyí ni ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ àti ìmọ̀ lítíréṣ̀ọ. Caudwell (1977.15) sọ pé:

> At one time, men are doing different things and therefore stand in relation to one another. The study of these human relations in general form s sociology.
>
> (Nígbà kan rí, àwọn ènìyàn ń ṣe nǹkan lọ́nà àrà ọ̀tọ̀ nítorí náà, wọ́n wà ní ìbáṣepọ̀ sí ara wọn. Ìmọ̀ nípa ìbára-ẹni-ṣe-pọ̀ yìí ní oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni Sociology)

Èyí ni pé ìmọ̀ nípa bí àwọn ènìyàn ṣe ń bá ara wọn ṣe pọ̀ láwùjọ ni Sosiọ́lọ́jì. Ẹ̀wẹ̀, A kò le ya lítíréṣọ̀ àti àwùjọ. Ìrírí ọmọnìyàn, òfin, ọ̀nà ìkọ́ni àwùjọ, àṣà, ìgbàgbọ́, iyì àti ẹ̀yẹ àwùjọ ni Sosiọ̀lọ́jì lítíréṣọ̀ ń lépa. Ó ń ṣe àwòjíìji àwùjọ ni gẹ́gẹ́ bí èrò Lious De Bonald (1954-1840), David Bleich (1976:7), Lawrenson and Swigwood (1971:107) àti Ogunsina (2006:6).

Tíọ́rì yìí gbà pé ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ kò dúró sí ojú kan, ó ń yí ni. Yíyí rẹ̀ le jẹ́ wẹ́rẹ́wẹ́rẹ́ tàbí gìrìgìrì. Ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tó ń yí ló mú ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wù wáyé tí ọ̀pọ̀ nǹkan kò fi rí bí wọ́n ṣe rí tẹ́lẹ̀. Oríṣirísị ni ìhùwàsí ẹ̀dà láwùjọ èyí tí ó hàn nínú àwọn ìwé òwe àti ewì tí a lò. Bákan náà ni àwọn onímọ̀ tíọ́rì tí a yàn lááyò gẹ́gẹ́ bi Hyppolyte Taine àti Escarpit (1968) nínú Pick (1971:10) gbà pé ìwé lítíréṣọ̀ kò jẹ mọ̀ iṣẹ́ ọnà alawòmọ̀ lítíréṣọ̀ nìkan bí kò ṣe ìgbéjáde, títà àti rírà ìwé lítíréṣọ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorì pé iṣẹ́ yìí jẹ mọ́ ìwé lítíréṣọ̀ tí àwọn òǹkọ̀wé kọ sórí àtẹ tí a sì ní láti lò fún ìkẹsẹjárí iṣẹ́ yìí.

Àlàbọrùndẹ̀wù àti iṣẹ́ àtẹ̀yìnwá

Ojú ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí àsìkò yówù ó jẹ́ ni Megahed and Ghoneim (2022) ní ìbámu pẹ̀lú https:www.dictionary.com fiwò àlàbrùndẹ̀wù nígbà tí wọ́nkì í pé: ‘New normal is a current situation, social custom e.t.c, that is different from what have been experienced or done before but is expected to become usual or typical’ (Àlàbọrùndẹ̀wù ni ìṣẹ̀lẹ̀, àṣà àwùjọ àti àwọn nǹkan mìíràn bẹ́ẹ̀ tí ó ń lọ lọ́wọ́ tí ó yàtọ̀ sí ìrírí tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àtẹ̀yìnwá ṣùgbọ́n tí a ti sọ di gúnmọ́ tàbí bárakú).

Ní ti Rahmoun, Hassan and Naddel (2023:2), ojú àjàkálẹ̀ àrùn kòrólá ni wan fi fún àlàbọrùndẹ̀wù ní oríkì. Wọ́n kì í gẹ́gẹ́ bi:

> New measures, policies or protocolsthat have an effect on the attitude andbehaviour of people in the field of publichealth after the covid-19 pandemic’

(ọ̀nà tuntun, ètò tuntun tàbí ìtẹ̀lé tuntuntó nípa lórí ìṣe àti ìwà ènìyàn nínú ètòìlera lẹ́yìn àjàkálẹ̀ àrùn kòrónà)

Ìyàtọ̀ nípa ojú ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí àwọn onímọ̀ wọ̀nyí fiwo àlàbọrùndẹ̀wù gẹ́gẹ́ bí oríkì tí wọ́n fún un ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ohun tí Adeyemi (2024:3) sọ nípa rẹ̀ pé 'kò fẹ́rẹ̀ sí oríkì kan pàtó tó gbé àlàbọrùndẹ̀wù (new normal) tan, ìhà tí ońmọ̀ kọ̀ọ̀kan bá kọ sí i ni'. Storm(2017),Jef (2021) àti Adéyẹmí (2024)ṣe àlàyé pé a ṣẹ̀dá àlàbọrùndẹ̀wù ní ọdún 2008 ní àsìkò tí àwọn ènìyàn fojú winá ètò ọrọ̀-ajé, ètò ìbákẹ́gbẹ́ àti àṣà àwùjọ tí ó dagun. Wọ́n ṣe àfikún pé ní ọdún 2020, ní àsìkò àjàkálẹ̀ àrùn covid-19 ni àlàbọrùndẹ̀wù sẹ́yọ tí olúkúlùkù sì ń wá ọ̀nà àbáyọ láti kojú àwọn ìṣòro tí ó bá ìgbà náà dé. Dasgupta àti Crunkhorn (2020) àti Jef (2021) ṣe àfikún pé ọ̀rọ̀ nípa àlàbọrùndẹ̀wù kì í ṣe ṣẹ̀ṣẹ̀ dé ní àwùjọ, ohun tí ó ti ń ṣẹlẹ̀ ti pẹ́ ni àti pé kì í ṣe ohun tí ojú kò rí rí. A fara mọ́ èrò yìí nítorí pé ìṣẹ̀lẹ̀ tó bójúmu àti èyí tí kò bójúmu ni ó máa ń wà ní àwùjọṣùgbọ́nìṣẹ̀lẹ̀ àìbójúmu àwùjọ kì í ṣe ohun tí ó ń mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ.Irú àwùjọ tí ìṣẹ̀lẹ̀ àìbójúmu bẹ́ẹ̀ bá wà kì í ṣe àwùjọ tó dára. Ìdí nìyí tí àwùjọ ṣe máa ń wá ọ̀nà láti kojú ìṣoro àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àìbójúmu bẹ́ẹ̀.

Nígbà tí Storm (2017) tọ́ka sí àlàbọrùndẹ̀wù nínú ètò ẹ̀kọ́, World Bank (2022a, 2022b, 2021a, 2021b, 2021c) ṣe àlàyé àlàbọrùndẹ̀wù nínú ètò ìlera. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé ohun tí àwọn tó ṣàlàyé àlàbọrùndẹ̀wù lókè yìí tẹpẹlẹ mọ nipé ìmọ̀ ẹ̀rọ ní ìlànà ìtàkùn àgbáyé àti àmúlò orísirísi ojú òpó ìkànnì látàrí àjàkálẹ̀ àrùn kòrónà ṣe ìrànwọ́ fún ìtalólobó àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lórí ọ̀nà àbáyọ sí àwọn ìṣòro sáà náà.

Adéwálé (2024:76-84) ṣiṣẹ́ lórí ewu tí ìtúká àti ìpínyà ìgbéyàwó ń mú bá àwùjọ lásìkò àlàbọrùndẹ̀wù.Ó ṣe àlàyé pé ògọ̀ọ̀rọ̀ ọ̀dọ́mọkùnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin ló ti ya ọmọ gànfé àti ọmọ ìta látàrí ìdílé tí kò tòrò. Ó tẹ̀ síwájú pé irú àwọn ọmọ wọ̀nyí ni wọ́n máa ń lu olùkọ́tàbí akẹ́kọ̀ọ́ ẹgbẹ́ wọn, àti pé irú àwọn tó jáde láti ìdílé tó fojú winá ìpínyà yìí ni wọn máa ń fi ilé ẹ̀kọ́ sílẹ̀ di alọ́nilọ́wọ́gbà ní ibùdókọ̀. Àkíyèsí nipé eku tí ó ta bá àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin ni ó fi ìrù na àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin tí wọ́n wà ní ipò náà tí wọ́n fi ń ṣe ṣìná tí wọ́n ń pe ara wọn ní olóṣó tí ọ̀gọ̀ọrọ àwọn ìyá-ń-dáágbé abíléko sì ń ṣe àgbèrè.

Oge ṣíṣe láàrin àwọn ọ̀dọ́ ní àsìkò àlàbọrùndẹ̀wù ni Osoba, Dina àti Ọlátúndé (2024: 138-150) gbé yẹ̀wò. Èyí ni àwọn ìyàtọ̀ tó bá oge ṣíṣe láàrin àwọn ọ̀dọ́ ní àsìkò náà. Wọ́n ṣe àlàyé pé orísirísi oge tí kò bá ti ayé àtijọ́ mu ni wọ́n yàn láàyò. Mustapha (2024:95-104) ṣiṣẹ́ lórí ìtẹ̀síwájú iṣẹ́ lórí gbogbo ẹ̀ka lítíréṣọ̀ Yorùbá ní àsìkò àlàbọrùndẹ̀wù

pàápàá ní àsìkò àjàkálẹ̀ àrùn kòrónà. Àkíyèsí wa ni pé iṣẹ́ yìí jẹ́ kía ní òye nípa pàtàkì iṣẹ́ lítíréṣọ̀ káàkiri àgbáyé.

Àṣàyàn Òwe àti Ewì Àpilẹ̀kọ Yorùbá tí ó tọ́ka sí ìlòÌpèdè Àlàbọrùndẹ̀wù

Kí àgbàdo tó dáyé, ohun kan ni adìyẹ ń jẹ, kí a sì tó ṣe òòṣà ni a ti ń ṣe oóṣá. Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni Yorùbá ti ní àwọn àròfọ̀ tí ó ń ṣe àfihàn bí nǹkan ṣe rínígbà kan, bí ó ṣe rí lọ́wọ́lọ́wọ́ àti ìhùwàsí ẹ̀dá nínú àwùjọ náà.

Lára àwọn àròfọ̀ bẹ́ẹ̀ ni a ti rí àwọn òwe tí ó sọ pé*kòní burú fún baba kí ó sọ pé ó dọwọ́ ọmọ òun lọ́run.*Nígbà tí ohun gbogbo rí bí ó ṣe yẹ kí ó rí, àgbàlagbà kì í ṣe ohun ìtìjú, àgbà a máa fi ara rẹ̀ sí ipò àgbà ni. Èyí sì ni Yorùbá fi ń sọ pé*ibi gẹ̀rẹ̀yẹ là ń bá àgbà* àti pé àgbàlagbà kì í ṣe langbalangbá tí ó túmọ̀ sí pé àgbàlagbà kì í wùwà àìtọ́. Ní báyìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwà tó yẹ ká bá lọ́wọ́ ọmọdé ni a ti ń bá lọ́wọ́ àgbàlagbà. Irú àgbàlagbà bẹ́ẹ̀ a sí di oníyẹ̀yẹ̀. Ìdí nìyí tí a fi rí òwe bí i àgbàlagbà tó só yangan mọ̀ ìdí ti di aláwàdà adìyẹ.

Nínú àṣà Yorùbá, ó ní bí a ṣe ń ṣe ohun gbogbo, Wọn a ní *ayé kò ní yí kí a fojú egbò tẹlẹ̀.* Ohun gbogbo ló ní ètò yálà àṣà ìgbéyàwó, ìsọmọlórúkọ, ètò ẹbí, ìkíni àti àwọn ètò inú àṣà Yorùbá gbogbo. Kò sí àtorípòdì tàbí àmúlùmálàní ọ̀rọ̀ wọn.Gbogbo wọn ló yanjú kedere. Láti fi ìdí èyí múlẹ̀, tí a bá wo òwe tí ó sọ pé àfàtiiri ni tiyàwó, bí a bá fà á tí kò bá tiiri, ó ní ohun tí ó ń wáa ó ri pé ní ayé àtijọ́ obìnrin máá ń tijú, yóò sì máa fi ọwọ́ wá ohun tí kò sọnù kiri lára ògiri ní ìgbà àkọ́kọ́ tí òun àti ọmọkùnrin bá pàdé. Èyí ni nígbà ìṣíhùn lábẹ́ ìgbésẹ̀ alárenà nínú ètò igbéyàwó. Àbí ti ìbálé ìyàwó tí kò fi bẹ́ẹ̀ jẹ́ dandan mọ̀ ni ká sọ ni, ohun gbogbo nípa àwọn nńkan wọnyí ti yàtọ̀ lásìkò àlàbọrùndẹ̀wù yìí. Kódà bí obìnrin pe ọkùnrin, kò lẹ́jọ́.

Bákan náà ni Yorùbá ní òwe tí ó sọ pé àìfàgbà fẹ́nìkan kò jáyé ó gún tàbí àìbẹ̀rù àgbà ni ò jáyé ó gúnní èyító jẹ́ pé ọmọdé kì í rí àgbà fín. Ọmọdé a máa bẹ̀rù láti rí àgbà fín nítorí kí àwọn náà le dàgbà. Ọmọlúàbí tilẹ̀ ti kógo ọ̀rọ̀ nípa ìwà já. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé ìwà lọba àwúre, wọn a sì tún máa sọ pé à ń tori ọmọlùàbí dára ni, a kì í tori ọmọlúàbí bàjẹ́. Kò sí ọmọdé tí yóò ṣe dáradára sí àgbà tí kò ní gba ìre. Yorùbá a tún máa pa òwe pé *ẹni a fẹ́ lóbìnrin ò fojú ire wo ni* tàbí *ẹni a yan ìyàwó ẹ̀ lálẹ̀ à á jìnnà si ni.* Ìbẹ̀rù gbọ́dọ̀ wà láti yan ìyàwó oníyàwó lálẹ̀ nítorí náà ni Ọkùnrin tó bá yan ìyàwó oníyàwó lálẹ̀ ṣe gbọ́dọ̀ jìnnà sí irú ọkọlóbìnrin bẹ́ẹ̀. Ìdí nipé ọkọlóbìnrin bẹ́ẹ̀ kò le fi ojú rere wòó, ó sì le ṣe àlè ìyàwó rẹ̀ léṣe.

Òwe mìíràn sọ pé àlàbọrùndẹ̀wù, àjíṣe di bárakú, ìbàjẹ́ wìn wọ́n

sí. Èyí ń ṣàfihàn pé ìwà ìbàjẹ́ ti i ṣe àgbèrè ti mọ́ àwọn mìíràn lára. Òwe mìíràn tilẹ̀ fi hàn pé ṣìná àti àgbèrè kò já mọ́ ohunkóhun. Kódà wọn a tún fi yagàn . Apẹẹrẹ rẹ̀ ni *ẹni tí a fẹ́ sọ pé a fẹ́ òun, ẹni ó fẹ́ẹ̀yàn sọ pé òun lòun fẹ́ ẹ, alajé wá ní kí wan ti ọ̀pá bọ̀ ọ́ kí a tún mú ajé sí i; kín lótún kù?*

Ọ̀rọ̀ ìbálòpọ̀ láàárín mọ̀lẹ́bí kò já mọ̀ ohunkóhun. Èyí ló bí òwe pé àìfọ̀rọ̀ lọ àgbà lọmọdé fi í bá ìyá rẹ̀ sùn. Ní àsìkò yìí ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ Yàhóò tí ó jẹ́ pé àwọn òyìnbó ni wọn ń lù ní jìbìtì tẹ́lẹ̀ kò rí àwọn òyìnbó lù ní jìbìtì mọ̀, ètùtù owó àti ìfinirúbọ ló kù tí wọn ń ṣe. ọmọ ń lo nǹkan ọmọkùnrin bàbá rẹ̀ nítorí àti lowó. Wọn kò ní olùbádámọ̀ràn gidi bí kò ṣe àwọn ẹgbẹ́ wọn àti oníṣegùn wọn

Wọ́n ní *a kì í mọ ọkọ ọmọ kí a mọ àlè rẹ̀* ṣùgbọ́n lóde òní, púpọ̀ nínú àwọn òbí pàápàá ni wọn kò ka mímọ àlè ọmọ wọn obìnrin sí ohun kan bàbàrà níwọ̀n ìgbà tí ọmọ bá ti ń mú owó wá fún wọn. Ọ̀nà kọ́nà tí àtijẹ àtimù yóò fi rọrùn ṣa ni tiwọn. Bákan náà ni a rí èyí tí ó sọ pé *aṣẹ́wó tí yóò kọ́ pẹ̀tẹ́ẹ̀sì, ó di dandan kí ìdí rẹ̀ ó dawọ.* Òwe yìí ń gbìyànjú láti fi ẹ̀rù sí ọkàn obìnrin tó nífẹ̀ẹ́ sí àgbèrè ṣíṣe láti má ṣe dán irú rẹ̀ láṣà ṣùgbọ́n ètò ọrọ̀ ajé orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tó wọ́ tí ọ̀pọ̀ yan iṣẹ́ aṣẹ́wó láàyò kò lé jẹ́ kí òwe yìí fi ẹ̀rù kankan sí ọkàn wọn. Irú obìnrin bẹ́ẹ̀ ti ṣe ìpinnu láti yan iṣẹ́ aṣẹ́wó láàyò nítorí àtijẹ àtimu àti láti gbọ́ búkátà.

Ètò ọrọ̀ ajé tí ó dorí kodò ni ó mú kí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn má le jẹun yó débi tí wọn yóò jẹun ṣẹ́kù. Tẹ́lẹ̀, ọ̀pọ̀ òbí a fún ọmọ lóúnjẹ yó dé ibi pé yóò jẹ ẹ́ ṣẹ́kù ní ìbámu pẹ̀lú òwe pé pé àjẹkù là á mayo. Bí ènìyàn kò bá yó, kò le jẹun ṣẹ́kù. ṣùgbọ́n báyìí, ọmọ ṣé o ti jẹun ló kù kò sí ọmọ ṣe o ti yó mọ́.

Ohun tí wọ́n bá pè ní èèwọ̀, ẹnìkan kì í dan wò. Ẹni tí ó bá jàjà ṣe ohun ìtìjú le gba ẹ̀mí ara rẹ̀ nítorí ìwọ̀sí àti ìdójútì àwùjọ. Àpẹẹrẹ èyí ni a rí nínú ìwà ọba Jáyin Aláàfin ọ̀yọ́ nínú ìtán gẹ́gẹ́ bí Jonson (2021:203) ṣe sọ. Ìṣẹ̀lẹ̀ náà ni pé ọba Jáyin pa ọmọ rẹ̀ nítorí owú. Àwọn ará ìlú gbé egúngún lọ ká ọbá Jáyin mọ́ ààfin. Ọkan nínú àwọn egúngún náà jẹ́ ti àwòrán ọmọ rẹ̀.Nígbà tí ọba Jáyin ri pé ìlú ń kó iwì bọ̀ wá ká òun mọ́ ààfin ni ó gba ẹ̀mí ara rẹ̀ nítorí pé ikú yá ju ẹ̀sín.Èyí ni ó sí fà ìpèdè pé ó kú dẹ̀dẹ̀ ká gbéwì dákẹ̀sán, ọba Jáyin tẹ́rí gbaṣọ. Nínú ewì *A-jí-gbọ́ toge*ìsàlẹ yìí, a ri pé ohun tí a bá pè ní èèwọ̀, ẹnìkan kì ídan wò.

Èèwọ̀ lèèwọ̀ jẹ́
Ajá ò gbọdọ̀ jobì

Ìpèdè ará ijọ́un nù un
Èèwọ̀ ṣá lèèwọ̀ jẹ́
Erin kì í joko abẹ́ ẹ̀
Ìyẹn láyé ijọ́un àná

Adebowale (2003:10)

Ohun tí a bá fi sọ́ wa, a kì í ji. A kì í ṣe ìbàjẹ́ pẹ̀lú ọmọ tó bá wà ní abẹ́ ìtọ́jú ẹni tàbí sàkání ẹni. Èyí kò rí bkẹ̀ mọ́ láyé òde òní gẹ́gẹ́ bí ewì òkè yìí.A rí àpẹẹrẹ bí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ṣe rí ní ìgbà kan lásìkò ọ̀pọ̀ oúnjẹ nínú ewì ìsàlẹ̀ yìí. *Nàìjíríà Dorí*:

… irè oko lohun àmúsọrọ̀ nípìlẹ̀ …
Sebigi oko ló ń fajé wọlé
Ọ̀pẹ pọ lọ jantirẹrẹ
Èpà pọ lọ jàra
Kòkó kò ṣe e kó tán lóko
Bẹ́ẹ̀ lòbítíbití gẹdú ń bẹ níjù …
Bọ́dún bá yí po lásìkò ìkórè,
Àlùpa loúnjẹ ọ̀hún lọ́jà …
Kò sẹ́ni ń làlàsí ohun jíjẹ
Kóówá ló ń jàjẹti

Adeleke (2005: 6)

Púpọ̀ ohun tí a kà sí èèwọ̀ ni ẹ̀dá kò kọ ibi ara sí mọ́. Ní àwùjọ tí a wà yìí, gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, baba ń bá ọmọ rẹ̀ lò pọ̀, ọmọ ń bá ìyá lò pọ̀, ẹbí ń bá ara lò pọ̀. Èèwọ̀, òhun ẹ̀gbin àti ìtìjú ni èyí láàrin Yorùbá. Ọ̀làjú àti àṣà ìgbàlódé ti kó àṣà àti ìṣe wa lọ gẹ́gẹ́ bí a ṣe ri nínú ewì *Ayé Dayé Òyìnbó* ìsàlẹ̀ yìí:

Ayé dayé Òyìnbó …
Lọ̀rọ̀ gbogbo wá doríkodò bí àdán
Ẹ wo bi ọ̀rọ̀ ọ̀làjú kó wa dé, ẹ ò réèmọ̀

Awolaoye *(2007:* 6)

Ewì òkè yìí fi yé wa pé ọmọ kó gbọ́ tòbí rẹ̀ mọ́ nítorí ìgbà tó wà níta tí wọn ń lò. Oríṣiríṣi ìwà kòtọ́ gbòde kan láàrin àwọn ọ̀dọ́ gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, ìjínigbé, ìfiniṣẹ́ṣọ́, ìfipá gbaṣọ oge lára omidan. Nígbà tí wọn ó bá wí, wọn a ní *ọmọ tí ayé bí layé ń pọn*. Àpẹẹrẹ èyí la rí nínú ewìÀbíìkọ́ Àkọ́ọ̀gbà:

Ọ̀rọ̀ ò kúkú sí lẹ́nu òbí olè
Bó tún wu ọmọ
A nà gẹ̀rẹ̀

A tún fọmọge tó lóhun ó fi ṣaya ṣowó

Aransi (2015:13-14)

Bákan náà nínúòwetó sọ pé *ayé bàjé olè ń dájọ*, ọ̀pọ̀lọpọ̀ arúfin ló ń lọ láìjìyà nítorí rìbá gbígbààwọn agbófinró. Bí ẹni tó bá mú arúfin kò bá ṣọ́ra, òun ganan yóò tún jẹ̀bi bọ̀. Èyí ló bí òwe mìíràn pé *bí* o bá bínú kínú, o ó jìyà kíyà, bó o bá jìyà kíyà, o ó jẹ̀bi kẹ́bi.Òtítọ́ kò sí mọ́, irọ́ ló kún ilé ayé.Òwe tó ṣàfihàn èyí nìòtítọ́ dọ́jà ó kùtà, owo lọ́wọ́ là ń rèkétàbíèké dáyé, aásáà dàpomu. Ó tilẹ̀ jẹ yọ nínú ewì *Abiyamọ*Ìwòyí ní ibi tí ìyá *Day care* kò ti fi òtítọ́ bá oníbàárà rẹ̀ lò.

Ìyá *Daycare* tí ń rọmọ lóògùn
Nítorí kó le ráyè ṣe tiẹ̀
Abiyamọ náà ṣá lòun

Adebowale (2003:25)

Èké ni ìyá *Day care* ṣe nínú ewì òkè yìí tó jẹ pé ìtọ́jú gidi ló ń fún ọmọ lójú ìyá rẹ̀, ṣùgbọ́n tí ìyá ọmọ bá lọ tán, ìtọ́jú òdì ló ń fún ọmọ. Awọn olórí wa gbogbo ń wu ìwà ta ni yóò mú mi, wọn a kówó ìlú jẹ, wọn a sọ mẹ̀kúnnù sínú ìyà. Bí ẹni tó fẹ́ ṣe rere tẹ́lẹ̀ bá dépò, òun náà a tẹ̀ síbi ayé tẹ̀ sí nítorí àsìkò tó wà níta ni wọn ń lò. Ohun tí wọ́n gbìn sí ọkàn ara wọn ni òwe tí ó sọ péẹ̣*ni oyè kàn tí ò ṣe ayé bó ti gbà, irú wọn ni ayé ń jẹ máye*.

Lákòótán, pẹ̀lú àlàyé àwọn òwe àti ewì òkè wọnyí, àlàbọrùn ti dẹ̀wù láwùjọ. Bó ṣe tọ́ kò sí mọ́, bó ṣe gbà ló kù gẹ́gẹ́ bí ewì *Bó ti gbà*ìsàlẹ̀ yìí:

Bótì tọ́ kò sí láyé mọ́
Ó ti kú láti ìgbà díẹ̀ sẹ́yìn
Bó ti gbà ló kù tó ń ṣègbà lóde
Ìgbà tó dé la ń bá yí
Ìgbà tó dé là ń lò

Sangotoye àti Owokunle (2017: 67)

Òwe àti Ewì Àpilẹ̀kọ Yorùbá tó tọ́ka sí Ìlò Ìpèdè Àlàbọrùndẹwú gẹ́gẹ́ bí Ọ̀nà Àbáyọ sí àwọn Ìwà kòtọ́ Àwùjọ.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe tọ́ka sẹ́yìn pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ kan wà tí kó rí bí ti í rí ṣùgbọn tí a gbà, tí ó sì di bárakú, àwọn tí kò bójumú nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà nílò ọ̀nà àbáyọ. Kí ojú má rí ibi, gbogbo ara ni oògùn rẹ̀. A rí àwọn òwe àti àwọn ewì Yorùbá tí ó ṣe àfihàn ọ̀nà àbáyọ lásìkò

àlàbọrùndẹ̀wù. Lára àwọn òwe bẹ́ẹ̀ ni*bí ó bá kọjú sí ọ kí o tá, bí ó bá kọ ẹ̀yìn sí ọ kí o ta, bí o bá ku ìwọ nìkan kí o tún èrò ara rẹ pa*. Òwe yìí ni pé kí ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú àwùjọ, àwọn ẹlẹ́gbẹ́-jẹ-gbẹ́ tó ń rí sí ìdàgbàsókè àwùjọ, àwọn ẹgbẹ́ajẹmẹ́sìn àti àwọn ìjọba wá ojútùú sí ọ̀nà àbáyọ sí ìpèníjà ọ̀kan-ò-jọ̀kan tóń ṣú yọ láwùjọ. Nípa ètò ọrọ̀ ajé tó dorí kodò, kí ìwà ìmọ̀ tara-ẹni-nìkan àwọn olórí dínkù, kí kóówá mú òwe tí ó sọ pé *ṣe bí o ti mọ, ẹlẹ́wà Ṣàpọ́n*ní ìbáádà.Kí ìtẹ̀síwájú wà fún ìfètò-sọmọ-bíbí àti oríṣiríṣi ọ̀nà rẹ̀ èyí tí ó ń dènà oyún àìròtẹ́lẹ̀ láàrin àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti abílékọ tí ó lè já sí ọmọ bẹẹrẹ, òṣì bẹẹrẹ.Nípa èyí, apá òbí yóò le ká bùkátà ìwọ̀nba ọmọ tí wọ́n bá bí, ìjọba pàápàá yóò le yanjú púpọ̀ ìṣòro ebi ọ̀pàgbà fọwọ́ mẹ́kẹ́ tí ó ń bá mẹ́kúnnù fínra. Iṣẹ́ àgbẹ̀ ṣe pàtàkì láti mú ní ọ̀kúnkúndùn.Ètò ìtọ́jú oúnjẹ nígbà ọ̀pọ̀ gbọdọ̀ jẹ ìjọba àti ará ìlú lógún.

Bákan náà ni òwe mìíràn sọ pé *bí a kò bá rí àdán, a ó fi òòbẹ̀ ṣẹbọ*. Èyí ni ṣíṣọ́ra fún wíwá tàbí ríra ohun tó wọ́n nígbà tí a le rí omíràn tàbí ra irú rẹ̀ mìíràn tí kò ní ni wa lára. Àpẹẹrẹ èyí jẹ yọ nínú ọ̀kan lára àwọn àkọlé ìwé ìròyìn Nigeria Sunday Standard (2023, September 17) tó sọ pé “Fertilizer scarcity: Farmers resort to human urine” (“Ọ̀wọ́ngógó fataláísà: Àgbẹ̀ fi àdàgbá ètò wọn rọ̀ sí lílo ìtọ̀ ọmọnìyàn”). Èyí ni ìlò ìtọ̀ ọmọnìyàn gẹ́gẹ́ bí fataláísà láti mú kí ilẹ̀ lọ́ràá dípòtí a ó máawá ọ̀wọ́ngógó fataláísà kiri. Àlàyé nípa àkọlé yìí tẹ̀ síwájú pé:

> The high cost of fertilizer which is going beyond the reach of an average farmer in Nigeria has forced the users to look for cheaper and environment friendly alternative source of growing their farm produce or risk being cut out of the farming business
>
> (Ọ̀wọ́ngógó fataláísà tí ó ṣòro fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àgbẹ̀ ilẹ̀ Nàìjíríà láti rà ti mú wọn wá ọ̀nà àbáyọ sí bí ohun ọ̀gbìn wọn yóò ṣe máa dàgbà tàbí tí wọn kò ní di àpatìnínú iṣẹ́ okòwò ọ̀gbìn).

Gbígbé àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá lárugẹ jẹ́ ọ̀ràn-an-yàn tí tolórí tẹlẹ́mù àti tonílé tàlejo àwùjọ gbọ́dọ̀ gbárùkù ti. Nínú àṣà Yorùbá ní a ti rí ìwà ọmọlúwàbí tíìtẹpámọ́ṣẹ́ àti ìtẹ́lọ́rùn wà. Èyí hàn nínúewì *Ọ̀làjú Òdì*tó wà ní ìsàlẹ̀ yìí pé:

Ẹ mójú tó tiwa-n-tiwa
Káyé ó le dára …

Ẹ jẹ́ ká káràmáàsíkì ohun tó bá jẹ́ ti ìbílẹ̀

Aransi (2015: 32)

Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ó yẹ láti fi àdúrà kún àwọn ìgbìyànjú wọ̀nyí látimú kí àwùjọ àti àwọn ènìyàn inú rẹ̀ jẹ́ èyí tí a ó le fi ṣe àwòkọ́ṣe nípa yíyàgò fún àwọn ìṣe àti ìwà kòtọ́ tó gbayé kan. Ewì *Bó ti Gbà*fi èyí hàn pé:

ká tún wá bẹ Olúwa Ọba
kó faniyọníbi ayé tẹ̀ sí ni
ká ké pe Aláwùràbí kò gbà wá lóko wàhálà

Sangotoye àti Owokunle (2017: 66-67)

Àgbálọgbábọ̀

Ìṣàmúlò àwọn ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wùnínú àṣàyàn òwe àtiewì àpilẹ̀kọ Yorùbá fún ìwúlò àti ìdàgbàsókè àwùjọ niiṣẹ́ yìí gbé yẹ̀wò. Iṣẹ́ yìí ṣe àfihàn àwọn ìpèdè àlàbọrùndẹ̀wù àti ìlò wọn. Ó àlàyé pé àyípadà ti bá ohun gbogbo ní àwùjọ pàápàá ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ó ṣe àlàyé ìlò wọn ní ìbámu pẹ̀lú bí nǹkan ṣe rí tẹ́lẹ̀ tí ó síbá ojú mu. Bákan náà ni ó ṣe àlàyé bí ó ṣe rí báyìí tí àlàbọrùn dẹ̀wù.Ó ṣe àlàyé àwọn ọ̀nà àbáyọ sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìwà tí kò bójúmu láti gbé wọ̀ bí ẹ̀wù pàápàá jù lọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Iṣẹ́ yìí ripé ṣàṣà àwùjọ ni kò ní ìṣòro nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìhùwàsí tó kù díẹ̀ káàtó ṣùgbọ́n bí ìpèníjà bá ṣe ń yọjú ni ó yẹ kí ẹ̀dá máa wá ọ̀nà àbáyọ. Bákan náà ni ó ripé bí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tilẹ̀ ń yí gẹ́gẹ́ bí àbùdá àwùjọ, àwọn ààyè àti ipò kan wà tí kò bá ojú mu fún ẹ̀dá láti yí sí.Iṣẹ́ yìí fi lélẹ̀ pé èyí tí ó bá dára nínú àwọn ààyè àti ipò náà ni kí ẹ̀dá tàbí àwùjọ dìmu.

ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adebowale, O. (2003) Ìgbà Lonígbàákà'. Ọ̀wọ̀: The Capstone Publications.

Adeleke, D. (2005). Naijiria Dori. Àwọn Akéwì Ń Sàsàrò.Ọ̀pádọ̀tun (ed.) Ibadan: University Press.

Adeyemi, L. (2024).Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Yorùbá Lásìkò Àlàbọrùndẹ̀wù.*Yoruba: Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria* 13(1): 1-33.

Aransi, O.A. (2015).*Ọmọlúàbí*. Ibadan: University Press Plc.

Awolaoye, O. (2007).Àkójọpọ̀ Ewì Àpilẹ̀kọ Fún Ètò Ẹ̀kọ́ Tuntun.

Ajiboye (ed) Ibadan: EMA Books.

Azeez, W. A. (2024). Ewu Ìtúká àti Ìpinyà Ìgbéyàwó Lásìkò Àlàbọrùndẹ̀wù. *Yoruba: Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria* 13(1): 76-84.

Babade, T. (2008).Àkójọpọ̀ Ìjìnlẹ̀ Òwe Yorùbá pẹ̀lú Ìtumọ̀ àti ìlò̀ wọn ní *Èdè Gẹ̀ẹ́sì.(Àkójọ kìn-ín-ní)*. Lagos: Yoruba, Proverb Research Project Publications.

Dasguta, S. and Crunkhorn, R. (2020).A History of Pandemics through the Ages and the Hjman Cost.*The Physician* 6(2). Pre-print vi epub 29.05. 2020 Doi: 10-38192/1.6.2.1.

Fertilizer scarcity: Farmers resort to human urine (2023, September 17). *Nigeria Sunday Standard*

Jeff, C (2021). Adapting to the culture of 'new normal' Anemerging response to Covid 19. *Journal of Public health* 43(2): 344-345.

Jonson, S (2021) *The History of the Yorubas.* Lagos. CSS Bookshops Limited.

Megahed, N., and Ghoneim, E. (2022). Blended Learning: The new normal for post-Covid-19 pedagogy. *International Journal of Mobile and Blended Learning,* 14(1), 16-32. Retrieved from https://doi?10.4018?IJMBL.291980.

Mustapha, M.O. (2024). Yorùbá Literature in the New Normal: The Pandemic's Preceedents. *Yoruba: Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria.*13(1): 95-104.

Oláwuyì, M.A. àti Ọládiméjì (2011).Àkójọpọ̀ Ẹ̀ẹ́dẹ́gbàáje Òwe àti Àṣàyàn Ọ̀rọ̀ *Yorùbá.* Lagos: Multiple Dee Nigeria Limited.

Ọ̀ṣọbà, B.K, Dina, S àti Ọlátúndé, C.O. (2024). Oge Ṣíṣe Láàrin Àwọn Ọ̀dọ́ní Àsìkò Àlàbọrùndẹ̀wù.*Yoruba: Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria* 13(1): 138-150.

Rahmoun, T.F, Hassan, M and Naddel, A. (2023).A Twin-Track Approach for Informal Settlements Restructuring in Response to the Impact of Covid-19: A Case Study in Muitidisciplinary Approaches to Organizational Governance During Health Crises. Retrieved from https://www.igi- global.com

Sangotoye, O. àti Owokunle, B.F. (2017) Ọ̀tọ̀lórìn (Àkójọpọ̀ Ewì Òde-Òní). Akure: Life Steps Publishers Ltd.

Sheba, J.O. (2006). Yoruba Proverbs with Feminine Lexix. Ibadan: Spectrum Books Limited.

Storm, S. (2017). The New Normal: Demand, Secular Stagnation and the Vanishing Middle-Class. *Institute for New Economic*

Thinking. Retrieved from https://www.inetconomics.org/perspectives/blog/the-new-normal.

World Bank. (2020, May 21). Supporting Workers' transition to a new normal amid COVID-19. World Bank Blogs. https://blogs.worldbank.org/en/voices/supporting-workers-transition-new- normal-covid-19

World Bank. (2020, September 28). Beyond COVID-19: What will be the new normal for health system and universal health coverage? World Bank Blogs. https://blogs.worldbank.org/en/health/beyond -covid-19-coronavirus-what-will-be-new-normal-health-systems-and-universal-health

World Bank. (2021, April). Remote Learning during COVID-19 pandemic. How contriesss have faced the challenge of implementing remote learning. World Bank Blogs. https://blogs.worldbank.org/en/education/remote- learning-during-covid-19-pandemic-how-countries-have-faced-challenge- implementing

World Bank. (2021,April 29). Three emerging digital technologies for the new normal in transport. Worldbank Blogs. https://blogs.worldbank.org/en/transport/three-emerging-digital-technologies-new-normal-transport.